koṣe ifẹ iyànjíjà ati ìjà nipa ọrọ eyi tí o nmú ilara, ìjà, ọ̀rọ̀-buburu ati ifurasi-buburu wá, (1 Kor 8:2; 2 Tim 2:14.)

5. Ati Ọ̀rọ̀ àyípo awọn eniyan ọlọ́kàn èérí ti kò sí otitọ ninu wọn, ti wọn ṣebi ọ̀nà si èrè ni ìwà-bi-Ọlọrun: yẹra lọdọ irú awọn wọnyìí. (1 Kor 11:16; Tit 1:11; 2 Pet 2:3.)

6. Ṣugbọn iwa-bi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrun èrè nla ni. (Filp 4:11; Heb 13:5.)

7. Nitori a kò mu ohun kan wá si ayé, bẹẹ ni a kò sì lè mu ohunkohun jade lọ. (Job 1:21.)

8. Bi a ba si ni ounjẹ ati aṣọ, iwọnyìí yoo tẹ́ wa lọrun. (Heb 13:5.)

9. Ṣugbọn awọn ti nfẹ di ọlọ́rọ̀ a maa bọ sinu ìdánwò ati ìdẹkùn, ati sinu wèrè ifẹkufẹ pupọ ti i pa-ni-lara, iru eyi ti o maa nri eniyan sinu iparun ati ègbé. (1 Tim 3:7; 1:19.)

10. Nitori ifẹ owó ni gbòngbò ohun buburu gbogbo: eyi ti awọn miran nlepa ti a si mu wọn ṣìnà kuro ninu igbagbọ, wọn sì fi ọ̀pọ ibanujẹ gún ara wọn lọ́kọ̀. (1 Tim 3:3; Jms 5:19.)

**Ọ̀rọ̀ iyanju fun Timoteu.**

11. Ṣugbọn iwọ eniyan Ọlọrun, sá fun nkan wọnyìí; ki o si maa lepa ododo, iwa-bi-Ọlọrun, igbagbọ, ìfẹ́, suuru, ìwà tútù.

12. Maa ja ìjà rere ti igbagbọ, di ìyè ainipẹkun mú ninu eyi ti a pè ọ sí, ti iwọ si ṣe ìjẹ́wọ́ rere niwaju ẹlẹri pupọ. (1 Kor 9:25,26; 1 Tim 1:18; Heb 13:23.)

13. Mo paṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ti nsọ ohun gbogbo di ààyè, ati niwaju Jesu Kristi, ẹni, niwaju Pọntiu Pilatu, ti o jẹri ìjẹ́wọ́ rere, (Jhn 18:37.)

14. Ki iwọ pa àṣẹ wọnyìí mọ́ ni ailabawọn, ni àìlẹ́gàn, titi di ifarahan Oluwa wa Jesu Kristi. (Filp 1:6; 2 Tess 2:8.)

15. Eyi ti yoo fihan ni ìgbà tirẹ, Ẹni ti i ṣe Olùbùkún ati Alagbara kanṣoṣo naa, Ọba awọn ọba, ati Oluwa awọn oluwa. (1 Tim 1:11,17; Ifh 17:14; 19:16;)

16. Ẹnikanṣoṣo ti o ni àìkú, ti ngbe inu ìmọ́lẹ̀ ti a kò lè súnmọ́, ẹni ti eniyan kan kò rí rí ti kò si lè rí: ẹni ti ọlá ati agbara titi lae nṣe tirẹ (Amin.) (1 Tim 1:17; Jhn 1:18; Ef 3:21.)

**Lilo Ọrọ̀.**

17. Kìlọ̀ fun awọn ti o lọ́rọ̀ ni ayé isinsinyìí, ki wọn maṣe gberaga, bẹẹ ni ki wọn máṣe gbẹkẹle ọ̀rọ̀ aidaniloju, bikoṣe lé Ọlọrun alaayè, ti nfi ohun gbogbo fun wa lọpọlọpọ lati lò; (Luk 12:20,21; A.A. 14:17; 1 Tim 4:10.)

18. Ki wọn maa ṣoore, ki wọn maa pọ̀ ni iṣẹ́ rere, ki wọn mura lati pín funni ki wọn ni ẹmí ìbákẹ́dùn; (1 Tim 5:10; Rom 12:8,13.)

19. Ki wọn maa to iṣura ìpìlẹ̀ rere jọ fun ara wọn de ìgbà ti nbọ̀, ki wọn lè di ìyè tootọ́ mú.

**Ọ̀rọ̀ Iyanju ikẹhin ati Oore-ọfẹ.**

20. Timoteu, maa ṣọ́ ohun ti a fi si itọju rẹ, yà kuro ninu ọ̀rọ̀ asán ati ijiyan ohun ti a nfi èké pè ni ìmọ̀; (2 Tim 1:14; 2:16.)

21. Eyi ti awọn ẹlomiran jẹ́wọ́ rẹ̀ ti wọn si ṣìnà ìgbàgbọ́, ki oore-ọfẹ wà pẹlu rẹ. Amin.

55

# TIMOTEU KEJI

**(A.D. 66)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini.**

PAULU, Aposteli Kristi Jesu nipa ifẹ Ọlọrun, gẹgẹ bi ìlérí ìyè ti nbẹ ninu Kristi Jesu (2 Kor 1:1; Ef 3:6; Tit 1:2.)

2. Si Timoteu, Ọmọ mi olufẹ ọ̀wọ́n: oore-ọfẹ, àánú ati alaafia lati ọ̀dọ̀

Ọlọrun Baba wa, ati Kristi Jesu Oluwa
wa. (1 Tim 1:2.)

**Ẹbẹ ati ọrọ iyanju si Timoteu.**

3. Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, ti emi nsìn
pẹlu ẹ̀rí-ọkan funfun gẹgẹ bi awọn
baba mi ti ṣe, pe ni àìsinmi lọ́sàń ati
lóru ni mo nṣe ìrantí rẹ ninu àdúrà mi
(Rom1:8,9;1Tess1:2,21;A.A. 20:37.)
4. Bi mo ti ránti omijé rẹ, bẹẹ ni mo nfẹ́
lati ri ọ gidigidi ki a le fi ayọ̀ kun mi; (2
Tim 4:9.)
5. Nigba ti mo ba rántí igbagbọ àìlé-
tàn rẹ, èyí ti o kọ́kọ́ nbẹ ninu Loisi
ìyà-nla rẹ, ati nínú Eunisi iyá rẹ; mo si
gbagbọ́ pé, o nbẹ ninu rẹ pẹlu. (1 Tim
1:5; A.A. 16:1.)
6. Nitori ìdí èyí ni mo ṣe nran ọ leti
pé ki o maa ru ẹ̀bùn Ọlọrun soke èyí ti
nbẹ ninu rẹ nipa igbọ́wọ́lé mi. (1 Tim
4:14.)
7. Nitori pe Ọlọrun kii fun wa ni ẹ̀mí
ibẹru; bikoṣe ti agbara, ati ti ifẹ, ati ti
iyèinú ti o ye kooro. Jhn14:27; Rom
8:15.)
8. Nitori naa, maṣe tijú ẹ̀rí Oluwa
wa, tabi emi òndè rẹ̀: ṣugbọn ki iwọ ṣe
alabapin ninu ipọnju ihinrere gẹgẹ bí
agbara Ọlọrun; (Rom 1:16; Ef 3:1; 2
Tim 2:2,9; 4:5.)
9. Ẹni ti o gbà wá là, ti o si fi ìpè
mímọ́ pè wá, ki i ṣe gẹgẹ bi iṣẹ wa,
ṣugbọn gẹgẹ bi ipinnu ati oore-ọfẹ
tirẹ̀, ti a fifun wa ninu Kristi Jesu lati
ayéraye. (Heb 3:1; Rom 16:25.)
10. Ṣugbọn ti a fihàn nisinsinyìí nipa
ifarahàn Jesu Olugbala wa, ẹni ti o pa
ikú rẹ́, ti o si mu ìyè ati àìdíbàjẹ́ wá si
ìmọ́lẹ̀ nipasẹ ihinrere. (Ef 1:9; 1 Kor
15:54.)
11. Fun èyí ti a yàn mi ṣe oniwaasu
ati aposteli ati olùkọ́. (1 Tim 2:7.)
12. Nitori ìdí èyí ti emi ṣe njiya
wọnyìí pẹlu: Ṣugbọn oju kò ti mi: ni-
tori emi mọ ẹni ti emi gbàgbọ́, o si da
mi loju pé, oun lè pa ohun ti mo fi le e
lọwọ mọ́ titi di ọjọ́ naa. (1 Tim 6:20;
Tit 3:8.)
13. Di apẹẹrẹ awọn ọ̀rọ̀ ti o ye koro ti
iwọ ti gbọ́ lọdọ mi mú, ninu igbagbọ
at ifẹ ti nbẹ ninu Kristi Jesu. (Rom
2:20; 1 Tim 1:14; Tit 1:9.)
14. Ohun rere ti a ti fi lé ọ lọwọ, pa
a mọ nipa Ẹmi Mimọ ti ngbe inu wa.
(Rom 8:9,11.)
15. Èyí ni iwọ mọ pé, gbogbo awọn
ti ó wà ni Asia yipada kuro lẹhin mi;
ninu awọn ẹni ti Figellu ati Hermo-
gene gbe wà. (A.A. 19:10; 2 Tim
4:10, 11,16.)
16. Ki Oluwa fi aanu fun ile Onesfo-
ru; nitori ti o maa ntù mí lara nigba
pupọ, ẹ̀wọ̀n mi ko sì tì í loju. (2 Tim
4:19.)
17. Ṣugbọn nigba ti ó wà ni Romu, o
fi ẹ̀sọ̀ wá mi, o sì rí mi.
18. Ki Oluwa fifun un ki o lè ri aanu
lọdọ Oluwa ni ọjọ́ naa, iwọ tikararẹ
saa mọ̀ dajudaju iye iṣẹ gbogbo ti o ṣe
fun mi ni Efesu. (2 Tess 1:10; Heb
6:10.)

## ORI 2.

NITORI naa iwọ ọmọ mi, jẹ ala-
gbara ninu oore-ọfẹ ti nbẹ ninu
Kristi Jesu. (2 Tim 1:2; Ef 6:10.)
2. Ati awọn ohun ti iwọ ti gbọ́ lọdọ
mi lati ọwọ́ ọpọlọpọ ẹlẹri, awọn naa ni
ki iwọ fi lé awọn olootọ́ eniyan lọwọ,
awọn ti yoo lè maa kọ awọn ẹlomiran
pẹlu. (1 Tim 6:12; 1:18; 1:12; 2 Tim
1:13.)
3. Ṣe alabapin pẹlu mi ninu ipọnju,
bi ọmọ-ogun rere Jesu Kristi. (1 Tim
1:18.)
4. Kò sí ẹni ti njagun ti nfi ohun ayé
yìí dí ara rẹ̀ lọwọ, ki o lè mu inu ẹni ti o
yàn an ni ọmọ-ogun dùn. (2 Pet 2:20.)
5. Bi ẹnikẹni bá sì ndije a kìí dee
lade, bikoṣe bi o bá pari rẹ̀ laiṣe èrú. (1
Kor 9:25.)
6. Àgbẹ̀ ti o nṣe làálàá ni o yẹ lati
kọ́kọ́ mu ninu awọn èso.
7. Gba ohun ti emi nsọ rò; nitori
Oluwa yoo fun ọ lóye ninu ohun
gbogbo.
8. Ranti Jesu Kristi, ti o jinde kúrò
ninu òkú, lati inu iru-ọmọ Dafidi gẹgẹ
bi ihinrere mi. (Matt 1:1; A.A. 2:24;
Rom 2:16.)

9. Ninu èyí ti emi nri ìpọ́njú titi de inu ìdè bí arufin; ṣugbọn a kò de ọ̀rọ̀ Ọlọrun. (A.A. 9:16; A.A. 28:31; Filp 1:7.)

10. Nitori naa mo nfarada ohun gbogbo nitori awọn àyànfẹ́; ki awọn naa pẹlu lè ni igbala ti nbẹ ninu Kristi Jesu pẹlu ogo àìnípẹ̀kun. (Ef 3:13.)

11. Otitọ ni ọ̀rọ̀ naa: Nitori pé bi awa bá ba a kú, awa o si baa yè.

12. Bi awa bá faradà, awa o si baa jọba: Bi awa bá sẹ́ ẹ, oun naa yoo sì sẹ́ wa. (Matt 10:33, 1 Pet 4:13.)

13. Bi awa kò bá gbàgbọ́, oun duro ni olootọ: Nitori oun kò lè sẹ́ ara rẹ̀. (Rom 3:3; Num 23:19.)

**Imọran Paulu si Timoteu.**

14. Nkan wọnyìí ni ki o maa rán wọn leti, maa kilọ fun wọn niwaju Oluwa pe, ki wọn o yẹra kuro ninu jijiyàn ọ̀rọ̀ ti kò léèrè, bikoṣe iparun fun awọn ti ngbọ́. (1 Tim 5:21; 6:4.)

15. Ṣaapọn lati fi ara rẹ hàn niwaju Ọlọrun ni ẹni ti o yege, òṣìṣẹ́ ti kò ni lati tijú, ti o npin ọ̀rọ̀ otitọ bi o ti yẹ. (Jak 1:12.)

16. Ṣugbọn yà kuro ninu ọ̀rọ̀ asán, nitori ti wọn yoo maa lọ siwaju ninu aiwa-bi-Ọlọrun. (1 Tim 4:7.)

17. Ọ̀rọ̀ wọn yoo si maa jẹ́ bi egbò kíkẹ̀; ninu awọn ẹni ti Himeneu ati Filetu wà; (1 Tim 1:20.)

18. Awọn ẹni ti o ti ṣina níti otitọ, ti nwi pe ajinde ti kọja ná; ti wọn si nbi igbagbọ awọn miran ṣubú. (1 Kor 15:12.)

19. Ṣugbọn ìpìlẹ̀ Ọlọrun ti o daju duro ṣinṣin, o ni èdìdí yìí, pe, "Oluwa mọ awọn ti i ṣe tirẹ̀." Ati pẹlu, "Ki olukuluku ẹni ti npe orukọ Oluwa kuro ninu àìṣòdodo." (Isa 28:16,17; Jhn 10:14; 1 Kor 1:2; 1 Tim 3:15.)

20. Ṣugbọn ninu ile nla, ki i ṣe kìkì ohun-èlò wura ati ti fadaka nikan ni nbẹ, ṣugbọn ti igi ati amọ̀ pẹlu; ati omiran si ọlá, ati omiran si àìlọ́lá, (Rom 9:21.)

21. Bi ẹnikẹni ba wẹ ara rẹ̀ mọ́ kuro ninu ìwọnyìí, oun yoo jẹ́ ohun-èlò si ọlá, ti a yà sọ́tọ̀, ti ó sì yẹ fun ilò baalé, ti a si ti pèsè silẹ̀ si iṣẹ rere gbogbo. (Isa 52:11; 2 Tim 3:17.)

22. Maa sá fun ifẹkufẹ èwe: si maa lepa ododo, igbagbọ, ìfẹ́, alaafia, pẹlu awọn ti nképe Oluwa lati inu ọkàn funfun wá. (1 Tim 6:11; 1:14; 1:5.)

23. Ṣugbọn ibeere wèrè ati alaini ẹ̀kọ́ ninu ni ki o kọ̀, bi o ti mọ̀ pe wọn a maa dá ìjà silẹ̀. (1 Tim 6:4; Tit 3:9.)

24. Iranṣẹ Oluwa kò sì gbọdọ jà; bikoṣe ki o jẹ ẹni pẹ̀lẹ́ si eniyan gbogbo, ẹni ti ó lè kọni, onisuuru, (1 Tim 3:3; 3:2; Tit 1:7.)

25. Ẹni ti yoo maa kọ́ awọn aṣòdì pẹlu ìwà tútù; boya Ọlọrun lè fun wọn ni ironupiwada si ìmọ̀ otitọ. (Gal 6:1; 1 Pet 3:15.)

26. Wọn o si lè sọjí kuro ninu idẹkun Èṣù, awọn ti a ti di ní igbekun lati ọwọ́ rẹ̀ wá si ìfẹ́ rẹ̀. (1 Tim 3:7.)

## ORI 3.

**Ikilọ nipa awọn ti yoo ṣe iyapa kuro ninu ẹ̀kọ́.**

ṢUGBỌN eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ ìgbà ewu yoo de. (1 Tim 4:1.)

2. Nitori awọn eniyan yoo jẹ olufẹ ti ara wọn, olufẹ owó, afunnu, agberaga, asọrọ-buburu, aṣaigbọran si òbí, alailọ́pẹ́, alâìmọ́. (2 Pet 2:3; Rom 1:30.)

3. Alainifẹ, alaile-dariji-ni, abanijẹ, alailè-kó-rawọn nijanu, ònrorò, alainifẹ-ohun-rere, (Rom 1:31; Tit 1:8.)

4. Onikúpani, alágídí, ọlọ́kàn giga, olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ. (Filp 3:19; 2 Pet 2:10.)

5. Awọn ti wọn ni àfarawé iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn ti wọn sẹ́ agbara rẹ̀; yẹra kuro lọdọ awọn wọnyìí pẹlu. (2 Tess 3:6.)

6. Nitori ninu irú eyi ni awọn ti nrákò wọ inu ile, ti wọn si ndi awọn obinrin alailọ́gbọ́n ti a di ẹ̀ṣẹ̀ rù ni igbẹsin, ti a si nfi oniruuru ifẹkufẹ fà kiri, (Tit 1:11.)

7. Wọn nfi igbagbogbo kẹ́kọ, wọ̀n

kò sì lè de oju imọ otitọ́. (2 Tim 2:25.)

8. Nję gẹgẹ bi Janesi ati Jamberi ti kọ oju ìjà si Mose, bẹẹ ni awọn wọnyìí kọ oju ìjà si otitọ: awọn eniyan ti inu wọn díbàjẹ́, awọn ẹni itanu niti ọ̀ràn igbagbọ. (Eks 7:11; A.A. 13:8; 1 Tim 6:5.)

9. Ṣugbọn wọn ki yoo lọ siwaju ju bẹẹ lọ: Nitori wèrè wọn yoo farahàn fun gbogbo eniyan gẹgẹ bi ti awọn meji yìí naa, ti yọri si (Eks 7:12.)

**Igbagbọ laika inunibini sí.**

10. Ṣugbọn iwọ ti mọ ẹ̀kọ́ mi, igbesi ayé mi, ipinnu, igbagbọ, ipamọra, ifẹni, suurù. (1 Tim 4:6; Filp 2:22.)

11. Inunibini, ìyà; awọn ohun ti o dé bá mi ni Antioku, Ni Ikonioni ati ni Listira; awọn inunibini ti mo faradà: Oluwa si gbà mi kúrò ninu gbogbo wọn; (A.A. 13:45; 14:2,19.)

12. Nitootọ, gbogbo awọn ti o fẹ maa gbé ìgbé-ayé iwa-bi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu yoo farada inúnibini. (Psm 34:19; Matt 16:24; 1 Tess 3:3.)

13. Ṣugbọn awọn eniyan buburu, ati awọn ẹlẹ̀tàn yoo maa burú siwaju si i, wọn o maa tan-nijẹ, a o si maa tàn wọn jẹ. (2 Tim 2:16; Tit 3:3.)

14. Ṣugbọn iwọ duro ninu nkan wọnyìí ti iwọ ti kọ́, ti a si ti jẹ ki oju rẹ dá ṣaṣa sí, ki iwọ si mọ̀ ọ̀dọ̀ ẹni ti iwọ gbé kọ́ wọn; (1 Tim 1:13.)

15. Ati pe lati ìgbà ọmọde ni iwọ ti mọ iwe-Mimọ, ti o lè sọ ọ di ọlọgbọn si ìgbàlà nipasẹ igbagbọ ninu Kristi Jesu. (2 Tim 1:5; Jhn 5:39.)

16. Gbogbo iwe-mímọ́ ni o ní imisi Ọlọrun ti o si ni èrè fun ẹ̀kọ́, fun ibani-wi, fun itọni, fun ìkọ́ni ti o wà ninu ododo: (Rom 15:4; 2 Pet 1:20,21.)

17. Ki eniyan Ọlọrun lè pé, ti a ti mura silẹ patapata fun iṣẹ rere gbogbo. (1 Tim 6:11; 2 Tim 2:2.)

## ORI 4.

**Ọ̀rọ̀ ìyànjú nipa ẹ̀kọ́ ti o yè koro.**

NITORI naa mo pàṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ati Kristi Jesu, ẹni tí yoo ṣe idajọ alààyè ati òkú, ati nitori ifarahan rẹ̀ ati ijọba rẹ̀. (A.A. 10:42; 1 Tim 5:21.)

2. Waasu ọ̀rọ̀ naa, ṣe aisinmi ni akoko ti o wọ̀, ati akoko tí kò wọ̀; bániwí, ṣe ìtọ́ni, gba-ni-niyanju pẹlu ipamọra ati ẹ̀kọ́ gbogbo. (1 Tim 5:20; 4:13; Tit 1:13.)

3. Nitori pé ìgbà yoo de, ti wọn ki yoo lè gba ẹ̀kọ́ ti o yè kooro; ṣugbọn bi wọn ti jẹ ẹni ti etí nrin, wọn o lọ kó olukọ jọ fun ara wọn ninu ifẹkufẹ ará wọn; (1 Tim 1:10; 2 Tim 3:1,6.)

4. Wọn o si yi etí wọn pada kuro ninu òtítọ́, wọn o si yipada si ìtàn asán.

5. Ṣugbọn maa ṣe pẹ̀lẹ́ ninu ohun gbogbo, maa farada ipọnju, ṣe iṣẹ efangelisti, ṣe iṣẹ iranṣẹ rẹ laṣepé, (A.A. 21:8.)

6. Nitori a nfi mi rubọ nisinsinyìí, àtilọ mi si sunmọ etile. (Filp 2:17; 1:23.)

7. Emi ti ja ìjà rere, emi ti pari iréìje mi, emi ti pa igbagbọ mọ́; (1 Tim 6:12; Filp 3:14.)

8. Lati isinsinyìí lọ a fi adé ododo lélẹ̀ fun mi, ti Oluwa onidajọ ododo, yoo fifun mi ni ọjọ́ naa kìí sì í ṣe kìkì emi nikan ṣugbọn pẹlu fun gbogbo awọn ti o ti fẹ ifarahàn rẹ̀. (Jms 1:12; 2 Tim 1:12; 1 Pet 5:4.)

**Ọ̀rọ̀ ipari: Ikini ati oore-ọfẹ.**

9. Ṣa ipá rẹ lati tètè tọ̀ mi wá.

10. Nitori Dema ti kọ̀ mi silẹ, nitori o nfẹ ayé isinsinyìí, o si lọ si Tessalonika; Kreskeni si Galatia, Titu si Dalmatia. (1 Kor 4:14; 1 Jhn 2:15.)

11. Luku nikan ni o wà pẹlu mi, mu Marku wá pẹlu rẹ: nitori o wulo fun mi fun iṣẹ-iranṣẹ. (A.A. 12:12; Kol 4:14; 2 Tim 1:15.)

12. Mo rán Tikiku ni iṣẹ lọ si Efesu.

13. Aṣọ òtútù ti mo fi silẹ ni Troa lọdọ Karpu, nigba ti iwọ bá nbọ̀ mu un wa, ati awọn iwe, pẹlupẹlu awọn ìwéawọ.

14. Aleksanderu alágbẹ̀dẹ bàbà ṣe mi ni ibi pupọ: Oluwa yoo san an fun un gẹgẹ bi iṣẹ rẹ: (A.A. 19:33; Psm 119:98,99; Rom 12:19.)

15. Lọdọ ẹni ti kí iwọ maa ṣọ́ra pẹlu nitori ti o kọ ojú ijà sí iwaasu wa pupọ.

16. Ni àkọkọ jẹ́ ẹjọ mi, kò si ẹni ti o ba mi gba ẹjọ́ rò, ṣugbọn gbogbo eniyan ni o kọ̀ mi silẹ̀: Adura mi ni ki a má ṣe kaa si wọn lọrun. (A.A. 7:60.)

17. Ṣugbọn Oluwa gba ẹjọ mi rò, o si fun mi lagbara; pe nipasẹ mi ki a lè waasu naa ni àwàjálẹ̀, ati pé ki gbogbo awọn Keferi lè gbọ́; a si gbà mi kuro lẹnu kiniun naa. (A.A. 23:11; 2 Pet 2:9.)

18. Oluwa yoo yọ mi kuro ninu iṣẹ buburu gbogbo, yoo si gbà mí dé inu ijọba rẹ ọrun: ẹni ti ogo wà fun lae ati laelae. (Amin.) (Psm 121:7; Rom 11:36.)

19. Kí Priska ati Akuila, ati ile Onesforu. (A.A. 18:2.)

20. Erastu wà ni Korinti: ṣugbọn mo fi Trofimu silẹ ni Miletu ninu àìsàn. (A.A. 19:22.)

21. Sa ipá rẹ lati tètè wa ṣaaju ìgbà òtútù. Eubulu ki ọ, ati Paudani, ati Linu, Klaudia, ati gbogbo awọn arakunrin. (ẹsẹ 9.)

22. Ki Oluwa wà pẹlu ẹ̀mí rẹ ki oore-ọfẹ wà pẹlu yin. (Amin.) (Gal 6:18; Film 25.)

56

# TITU

**(A.D. 65)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

PAULU, iranṣẹ Ọlọrun, ati Aposteli Jesu Kristi, gẹgẹ bi igbagbọ awọn ayanfẹ Ọlọrun, ati ìmọ̀ otitọ ti nbẹ gẹgẹ bi iwa-bi-Ọlọrun, (Rom 1:1; 2 Kor 1:1; 1 Tim 2:4; 6:3.)

2. Ninu ireti ìyè ainipẹkun, ti Ọlọrun, Ẹni ti kò lè ṣèké, ti ṣe ileri ṣaaju ipilẹṣẹ ayé; (2 Tim 1:1; Rom 16:25.)

3. Ṣugbọn ni akoko tirẹ̀ o fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ hàn ninu iwaasu, ti a fi le mi lọwọ gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun Olugbala wa; (2 Tim 1:10; 1 Tess 2:4.)

4. Si Titu, ọmọ mi nitootọ́ nipa igbagbọ ti i ṣe ti gbogbo eniyan: oore-ọfẹ, ati alaafia, lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun Baba wa ati Kristi Jesu Olugbala wa. (2 Kor 2:13; Ef 1:2; 1 Tim 1:2.)

**Iwa ti o tọ fun awọn alàgbà.**

5. Nitori idi eyi ni mo ṣe fi ọ silẹ ni Krete, ki iwọ lè ṣe ètò ohun ti o kù, ki o si yan awọn alàgbà ni olukuluku ìlú, bi mo ti paṣẹ fun ọ, (A.A. 27:7; 14:23; 11:30.)

6. Bi ẹnikan ba ṣe aláìlẹ́gàn, ọkọ aya kan, ti o ni ọmọ ti o gbàgbọ́, ti a kò fi sùn fun wọbia, ti wọn kò sì jẹ́ alagidi. (1 Tim 3:2–4.)

7. Nitori pe o yẹ ki bisọbu jẹ́ alailẹ́gàn, gẹgẹ bi iriju Ọlọrun; ki o má jẹ aṣe-tinu-ẹni, oninu-fùfù, ọ̀mùtí, aluni, olojukòkòrò; (1 Kor 4:1; Ef 5:18.)

8. Bikoṣe olufẹ alejò ṣiṣe, olufẹ awọn eniyan rere, alairekọja, olootọ́, ẹni mímọ́, ẹni ìwọ̀ntúnwọ̀nsì; (1 Tim 3:2; 2 Tim 3:3.)

9. Ti o ndi ọ̀rọ̀ otitọ mu ṣinṣin eyi ti i ṣe gẹgẹ bi ẹ̀kọ́, ki oun lè maa gba-niniyanju,ninu ẹ̀kọ́ ti o yè kooro, ki o si lè maa dá awọn asọrọ-òdì lẹ́bi. (1Tim 1:19; 1:10.)

**Paulu sọ nipa awọn olukọ èké.**

10. Nitori pe ọpọlọpọ awọn alagidi, awọn asọrọ asán, ati awọn ẹlẹtan ni nbẹ, paapa awọn ti ikọlà; (1 Tim 1:6; A.A. 11:2.)

11. Awọn ẹni ti a nilati pa lẹnu mọ́, awọn ẹni ti nda odidi agbo ilé rú, ti wọn nkọni ni ohun ti kò yẹ nitori èrè àìtọ́. (2 Tim 3:6; 1 Tim 6:5.)